ASOJE ORO

Bi a ba wo gbo gbo erun ti o ngku pa da, se owo ...wa l'o ti nwa ba ni. Olorun ko ... da akuec beni 'o da warapa, ohun ti a ba se l'o nfa iku ba ni.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

YORUBA

VOL. XII No. 682 LAGOS, SATURDAY, JULY 2nd — JULY 8, 1960 KOBO MEJI 2D

# GONGO SO ! NI ILORIN — Egbe Igbomina Parapo Gbe Egbe Olomi Subu

**ILORIN** Ninu gbogbo ibo igbimọ ibilẹ ti wọn di kọja laipẹ yi, ni ẹkun ilu Ilọrin, awọn ilu bi mẹje ni won dibo yan awọn enia sinu igbimọ ibilẹ ilu wọn. Ẹgbẹ Igbomina Parapọ ti wọn jẹ ẹka ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group Alliance) ni o bori ninu awọn idibo na.

Awọn ilu bi Oke-odẹ, ni adugbo Ọba, Amubi Agoda, Shata, Makun, Ẹlẹiyẹle, Alabẹ ati Asọnlu, ẹgbẹ Olomi ko r'ọwọ yo gbe ẹgbẹ Igbomina Parapọ l'o gake to yọ bi osu.

Eyi jẹ ibo akọ di, o ku ti ẹkeji ti awọn Alaṣẹ Ijọba ko iti da ọjọ didi ibo ti ẹkeji na.

**AYIPADA RERE NWOLẸ ENIA DUDU**

Ghana Di Ilu Alaṣẹ Arare

Lọjọ jimọ (Friday) ti ana, ti iṣe ọjọ kini oṣu July, 1960 yi ni ilẹ Ghana. ti a ti npe ni Gold Coast ri, di ilu Alaṣẹ ararẹ (Republic) Dokita Kwame Nkrumah ni awọn yan ni Baba Ẹgbẹ Alakoso ilu Ghana. (President of the Republic of Ghana).

(Wo yoku loju ewe kejọ)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN CITY, WARRI
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Nathanign London.
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## Oloye Basorun Oyo D'ologbe

Igboro ilu Ọyọ mi titi, nigbati awọn tu ọfọ iku Oloye Joanes Ladokun ti iṣe Oloye Baṣọrun ilu Ọyọ. Oloye na jẹ ọkan pataki ninu awọn igbimọ Lọbalọba lati ọdun 1956. O ṣalaisi nigbati o dagba di ẹni ọdun mẹrinlelogọrin.

Ọmọ ti Baṣọrun fi silẹ laiye jẹ ọmọ mẹwa, ṣugbọn awọn ọmọ ọmọ rẹ jẹ ogbọn. Nwọn sinku rẹ si agbole Baṣọrun gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ.

A si gbọ wipe, nigba ewe Baṣọrun na, Iewe Agunda lo gbe kọ̀e, o si jẹ oye Baṣọrun Ọyọ ni odun 1936.

Ọlọrun ko fi orun kẹ.

## Okun Japan Le Papo

Okun Pacific ti a pe ni okun ilẹ Japan, Kaiyo Japan tikan lo mbọ ni ẹẹ ọdun yi, China paapa wa nibẹ, apakan ilẹ Korea wa, apakan Malaya wa nibe pelu bẹni awọn erekuṣu Phillipines wa pẹlu.

Ọdun kan ko le dan ki a ma se gbọ iro jamba lati okun yi, gẹgẹbi lamba ...l'e (Typhoon) Ẹkunmi (Ocean) Efufu ... (Storm) jabi iṣẹlẹ (Earthquake)

A gbọ lẹẹu awọn Oyinbo wipe ilẹ Japan ni iba derajulo ni gbogbo aiye, ti o ba jẹ wipe, iru awọn jamba ti a darukọ rẹ awonyi ko ba a jẹ.

Idi re ti jamba ṣe ma ... ni'le Japan papọju ni wipe iru oke kan ti o ma fi gbogbo ọjọ ru nafi inde ti awọn Oyinba npe ni Volcano pupọ ju ni ilẹ na.

Laipẹ yi, ọkan ninu awon erekuṣu Phillipines, ti a npe ni Manila ni ẹfufu buruku na pa enia meji, o gbe enia merinlelogun lọ. Ọkẹ meji abọ enia lo di alai rile gbe mọ.

## Alakoso Ile Liberia Nilu Ibadan

Nigbati Baba ẹgbẹ ti iṣe Alakoso ilẹ Liberia William Tubman de ilu Ibadan awon enia ti a nwo awọn an won ninu iwe yi ni awọn Minni



## Won Fi Oba Ilu Kan Sun Esun Ole

Ni ilu kan, ni ipinlẹ Ila-Orun, awọn ara ilu na ma nmu ẹjọ lọ si ọdọ ọba ilu wọn, ki o le pari rẹ fun wọn, nitoripe awọn gbagbọ pe ẹsin ile yaju ẹsin ode, awọn ko si nfẹ ki alejo tabi ki ajeji mọ ohun ti awọn nṣe, ayafi awọn ara wọn.

Nitorina bi enia meji nja, ọba ni yio sọ pari fun wọn. Bi o ba si ti sọ si ni awọn o gba. Bi ole ja, on ni yio da ẹjọ rẹ. Nigbati ẹṣinṣin njẹ elegbo, ẹnikan ko gbọ ṣugbọn nigbati elegbo wa jẹ ẹṣinṣin san, nigbana ni ariwo ta wipe lagbaja njẹ ẹṣinṣin. Bayi ni ọna na nṣe fun awọn enia rẹ

Lọjọ kan ni ọba na papaa wa lọ ji ẹrọ itẹwe ti awọn ẹgbẹ kan ti o jẹ ọmọ ilu rẹ fi nte iwe (Typewriter). Nigbati awọn ko ri ẹrọ itẹwe na, awọn lọ fi ẹjọ sun ọba. Nigbẹhin ni awọn ri i lọwọ ọba wọn nibiti o gbe nlo ẹrọ na.

Nwọn gbe ẹjọ na lọ si ọdọ Oyinbo. Gbogbo awọn to ti ọba na lojọ ti awọn ra a mu lo njapa mọnu wipe, h nia! ọwọ Ọlọrun tẹ ọba wọn, ṣe nigbati o dajọ fun wọn nijọsi abosi lo ṣe fun wọn.

Ọpọlọpọ awọn enia pataki ninu awọn ti oba yi ti dajọ fun ṣiwaju ri odide tẹle oba na lẹhin lojo ti Oyinbo ni ki ọjọ kan lọ mu wa.

Nigbati ẹjọ na dewaju adajọ kotu ijoba adajo so fun wipe, o jẹbi tabi o ko jẹbi? Oba na so fun pe on ko jẹbi. Adajo bere nibo lo gbe ti ri ẹro itẹwe na? O dahun pe omọ on lo ra fun oh. Ọmọ na nkọ, nibo lo gbe wa? O dahun pe, o ti lo si Eko.

Nibo ni adajo ti pa owe yi pe. "Ẹniti a nk o kinniọla fi ẹgun si owo, ẹniti ani ki o fẹ ni loju fi ata si ẹnu, ẹniti a ni ka fi ehinti ki a mu didun ẹnu, ganin-ganin lo nfun ni mu.

Nitorina, on yẹ ẹjọ na si ibẹrẹ oṣu July ki o ranṣẹ si ọmọ rẹ na ni Eko, ki o tete de, adajọ ni ki nwọn gba kuro fun.

---

## Ohun Awon Adajo Ko S'okan Lori Ija Dick Tiger

Ni ilu Amẹrika lọhun ni ọmọ ilẹ Nigeria kan ti lọ ba wọn ṣe ere ẹṣẹ kikan, ti a npe orukọ rẹ ni Dick Tiger. Ilu Oyinbo lo kọkọ lọ ti okiki rẹ si bẹrẹ si kan, nigbati iroh in rẹ de ilẹ Amẹrika lọhun, ni nwọn ba ranṣẹ si pe ki o ma bọ wa danrawo ni ọhun.

O de ilẹ Amẹrika na to iwọn ọjọ mẹta, ti o si nyi wọn molẹ. Ọkunrin kan wa nilu Canada ti o lẹ ẹniti o le ja gẹgẹbi Dick Tiger, ati wipe ẹgbẹ kanna ni awọn mejeji jẹ, orukọ rẹ ni Wid Greaves, o ti ja, ja, ja, o si ti di ọkan ninu awọn akọni aiye, nwọn ni ki Ọgbẹni Dick Tiger wa ba ọkunrin na kojo ija ki o le gba oye Akọni aiye kuro lọwọ ọkunrin na.

Lori ija na ni a gbọ wipe ẹnu awọn adajọ ere na ko ṣe ọkan si, Ni akọbẹrẹ ere na, nwọn fi Dick Tiger ṣe aṣoju Gẹsi nwọn si fi alatako rẹ ṣe aṣoju ilẹ Amẹrika.

Ni akọko, awọn adajọ ere na sọ wipe dogbadogba ni ija awọn mejeji, ẹnikan ko mu ẹnikan.

Sugbọn awọn ẹgbẹ elere ẹṣẹ kan ti nwọn npe ni igbimọ Edmonton Boxing Club sọ pe awọn kolti le da ẹjọ na, awọn yio ro o na.

Awọn ero iworan ti nwọn wa ni alẹ ọjọ na le ni 3,500 Gbogbo enia lo ro pe wa sibi ija nigbati nwọn gbọ pe dogba-dogba ni ija na.

Ọkan ninu awọn adajọ ti o wa sibi ija alẹ ọjọ na ni Doctor Louis Schwarty lo kọkọ dajọ wipe, ni ti on, on gba wipe Ọgbẹni Dick Tiger bori ere ẹṣẹ alẹ ọjọ na. Adajọ keji ni Doctor Les Willicks sọ wipe, on gba wipe Wid Greaves, alatako Dick Tiger lo bori ni alẹ ọjọ na. Ṣugbọn alabojuto ija na (Referee) sọ wipe ninu akosilẹ ti on, dogbadogba ni on ko silẹ 5-5-5.

Nitorina idajọ awọn adajọ mejeji pare, sugbon ki o ma ba si edekoyede, nwon fi okan kun ti Greaves tirẹ di mẹfa, nwon ko din ti Tiger ku mẹrin ti o ku nilẹ jẹ dogba-dogba.

---

# Enia Dudu Fi Aso Riro Han Ni Afin Oba GESI



Obinrin ti a nwo, ti o ro dede ti o si gba dede ninu aworan yi ni, Iyafin P. Ṣosanya, ọmọ ilẹ Nigeria ti o wa sibi apeje kan ti awọn ṣe ni Agbala Afin Ọba nigboro ilu London.

Nigbati awọn ero ti nwọ sibi apeje na tan, ni Ọba Gesi, Elisabeth Keji, ati Iya Ọba, ati Ọba ati Ọmọba binrin Alexandra ti o mbọ wa ba wa yọ awọn Ọmọ wa ninu oṣu October, jade wa ki olukuluku awọn ti o wa sibi apẹjẹ na.

## Ode Kan Yinbon Pa Kiniun

(Apa Keji)

Lati ọwọ ẹṣẹ

Nigbati olukuluku awọn ọdẹ gbero igbe Onigbogbagbo, gbogbo awọn ti o nwoko ṣe wẹn! bi ọbẹ panu, olukuluku si nwa ọna bi yio ti ṣe sa asala kuro ninu igbo na, ki o ma ba bọ si ọwọ akọ ẹran ti o gbọgbẹ na.

Ọpọ ninu awọn ọdẹ ti o sala na yọ si abule kan ti nwọn npe ni Odo-Ọba, ibẹ ni awọn ọdẹ yoku ti mba ara wọn. Awọn ọdẹ ti o ti yinbọn wọn gbe ẹran ti wọn pa ti si ẹgbẹ kan, nwọn si tun ibọn wọn ki.

Nwọn wa mbere wipe tani ri ẹranko, tabi iru ẹranko wo ni o ri? Ẹniti o kigbe wipe Onigbogbagbo dahun wipe, emi ni mo kigbe bẹ, kiniun ni mo si ri ti o nsare lọ niwaju mi, ko ju iwọn iṣẹju meji lọ lẹhin ti mo gburo ibọn meji.

Nwọn bere pe tani yinbọn na? O dahun pe on ko mo. Awọn ọdẹ bẹrẹ si yọ jade ni ọkọkan nigbati o to bi iwọn wakati meji ti nwọn ko ri awọn ọde yoku nwọn fi ohun ṣọkan wipe ki olukuluku ki ibọn rẹ ni ikamarun-marun ki nwọn jẹki a lọ wo awọn ọdẹ ti o ku ni abule keji.

Ṣamọṣamọ ọdẹ ti o ni ibọn oyinbo lo yinbon si ẹranko na. Bi awọn ọdẹ yoku ti nwa a kiri bẹni on na nwa wọn kiri.

Nibiti o nwa awọn ọdẹ yoku kakiri, o ia soju ọna kan o nlọ ni o si ti nlọ lo tun lọ ṣe pẹkirẹki kiniun ti o yinbọn fun nibiti o gbe atorugbe oju rẹ mejeji ni ibọn ti bajẹ ibọn si tun ba ni ibaradi.

Ọdẹ onibọn oyinbo tun yin ibọn meji lu ẹranko na o tun fi igbe ta wipe Onigbo gba-gbo-o!

Bi ọdẹ ti nlọ ninaji ti o nwa awọn ẹgbẹ rẹ lọ, bẹni awọn ọdẹ y ku nwa on na bọ lẹhin. Bi o ti ku diẹ bi iwọn adọta ẹsẹ ki nwọn kan ara wọn ni nwọn tun gburo Onigbogbagbo

Bayi ni gbogbo awọn ọde tun sare pada si abule Odo-Ọba, nibi ti ọlẹ Onibọn Oyinbo ... na wọn.

Nwọn bere lọwọ rẹ pe, iru ẹranko wo lo yinbọn fun? O si dahun wipe, emi na paapa ko ri iru ẹranko na ri, ṣugbọn o ni iru gigun gẹgẹbi ti ẹṣin, o si ni jọjọ lọrun gẹgẹbi ti ẹran agbo.

Alagba ọdẹ kan ti iṣe ara ilu Awẹ sọ wipe, ẹ wa o "gbami-gbami ko yẹ egba kini kan nle mi bọwa ko yẹ ọdẹ", jẹki olukuluku ki ibọn rẹ, ki a si pada si ilu iwo, ohunkohun ti o ba de ki a jijọ ja.

O tun di ọsẹ ti o mbọ.

## Sir Abu Bakar Ati Sir James Gba Alejo Nla



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Sir Abu Bakar ti iṣe Prime Minister ile Nigeria, on pẹlu Sir James Robertson Gomina agba gba Ọgbẹni Tubman President ilu Liberia ti ilelo wa de Gomina. Pẹlu bi ọjọ ti npon bi emi loro ti Alagba na de, awọn enia fi tayo-tayo ki i pe o ku abọ.

Nigbara ti Baba ẹgbe na gunlẹ si ebute Ehoghori ni awọn ro agba iṣọkanlọlọrgun ni Apapa ... ki alejo na k'abọ.

(Wo yoku oju ewe kẹrin)

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLD AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 24, Balogun Street Lagos

# ELETI-OFE

A-NJUWON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
, Kosoko Street, Lagos. "ELETI — OFE, LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII NO 682 SATURDAY JULY 2. — JULY. 8, 1960


# Eyi To 'Ronu Feni To Moye

Gbolohun akole oro orin awon Oniwaka Musulumi ti a fi se esin wosika wa ose yi fun enyin okawe wa ni o jade le'u wa nigbati a bere si ro iau wa wo lori iwa abuku, iwa abeşe, iwa ipata ati ipanis, iwa buburu ti ko ye omo enia, ti awon odomokunrin ilu Eko wa yi nhu laibikita ati aini ibẹru Olorun ati enia lekan.

"Die ni ti Alaba ninu ibeji", ni a le pe ti awon Orogun wa nipa esin, iyen ni awon elesin Igbagbo (Christians) ti awa Imale ni o buaya ti o si le gongo ninu oro na, nitoripe bi o ba gbo wipe omo kan gbe Egungun fi ho'wa janduku, omo Imale ni wa ba nibe, bi o gbo wipe omo kan gbe Agemo fi se jamba fun enia laria ilu, omo Imale ni wa ba nibe. Kilose? "awon ha le peni l'ole, ki a tun ma gbe omo eran jo". Ki awon pe wa ni Imale, ki a si so di Imolile.

Kosi ohun kan ti o ba ti je ona iborişa tabi Awo, ( Cult ) ona ti o lodi si ofin Alukurani mimo ti a wipe a gbagbo, agbarakaka ni o le fi ri omo Kiriyo nibe, sugbon niti omo Imale, jaburata ni eo ri won nibe. Eniti ise'e ti awon to gbe Agemo l'ale ojo nisun odun titun ni akan bi ogun odun sehin, ti awon olopa fi ra opolopo omo Imale mu fi sun esun ipania wipe awon lu okunrin kan ti oruko re nje Bello Erogbogbo pa ni adugbo kan ni Epetedo ko ni sai jeri si oro wa.

Bakanna niti awon Alawo Opa (Cult) ti awon se'ku pa Alufa Apalara ni Oke Ebute Metta, ti odidi enia mokanla fi di yiyegi molese pa, omo Imale ni o poju ninu won. Howu ! "Bi oju ko ba ti ole, o ye ki oju ti awon enia re ".

Loni talo gbe Egungun ? Rasaki ni, l'ola talo gbe Agemo ? Suberu ni, beni Rasaki ati Suberu, oruko Imale ni won. Ki o je pe alo, alo. gbogbo iwa buburu ko ni se lori omo Imale. Enyin obi omo. baba ati iya nje eyi ko ha to irona fun nyin bi ?.

Asiko na to fun wa nisisiyi gegebi Musulumi ododo ti a ngb'orun ominira ile wa Nigeria yi, lati m'ojuto awon omo wa ti awon nfi iwa buruku se ayo yo wonyi, nitoripe awon ologbon Yoruba ni o ma npa lowe wipe, "Ohun ti o yeni l'o yeni, okun orun ko ye adie."

Eyi to'ronu feni to m'oye.

# AWON ONI BODE ILU OYINBO



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon osise Bode nilu Oyinbo, ibi awon ti nko eru sile beni awon nfi moto ko lo sile ifipamosi, akowe Bode kan si duro ti won

## SIR ABU BAKAR ATI SIR JAMES GBA ALEJO NLA

(Obere lojo ewe keta)

Awon Omo ogun ile wa kan ti a npe ni H.M.N.S. Nigeria ni o lo pade alejo na ti o mbo wa larin agbami rere okun Alasia, on ni o si se amona Oko alejo na wo ona kuro ninu okun wa gunle.

Lehinni alejo wa na ti ki awon omo ogun oju omi tan ni Gomina-agba mu sinu moto, o si mu lo sile. Nigbati o dele ni Sir Abu Bakar fi iwe ikini ku abo ki i.

Ni ale ojo ti o de ni o gba origirisi alejo, awon asoju ilu okere ti o wa l'Eko.

O lo ba awon Oniwe Irohin se ipade ninu ile igbimo. Gomina agba se ase nla repete kan fun ni ile Gomina, (State Dinner) nibe ni o koko nba Gomina agba soro.

Die ninu awon ibiti o de si wonyi:- O de Obalende ni ago olopa, o lo si Sola Idumota o je ase ni Lagos Town Council, gbogbo awon ara ilu Liberia ti o wa ni Eko wa jo fun u. Awon gbajumo ilu Eko ba se faaji ni Island Club. Sir Abu Bakar se ase onje ale fun u, lehinna lo kori si ona Ibadan.

## Iponrinku Pa Elenmo

Egungun kan wa ni Ibadan ti awon npe ni Elenmo. Bi egungun Elenmo yi ba jade ko si egungun miran ti o gbodo jade lojo na, obinrin ko si gbodo fi oju ri,

(Wo yoku loju ewe keje)


Plushes, Velvet, Velveteens Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street (Faji Market)
LAGOS NIGERIA

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## Prime Minister Ile Japan Binu Fi Ise Sile

Agbo irohin wipe, bibọ ti Ogbeni Eisenhower mbọ silẹ Japan, ko si ẹniti o le sọ kini igbẹhin rẹ yio ti ri bi ọkunrin na ba fi ẹsẹ tẹ ile Japan. Ṣugbọn nitoripe ki o ma ba si ogun tabi ote, ni ọba ilu Japan Hirohito ati Prime Minister wọn Ogbeni Nobusuke Kishi se dide ti nwọn si lọ pade Ogbeni Eisenhower ni okun ilẹ China, ibe ni nwọn ti ba ara wọn muilẹ ọrẹ ti o si pada sẹhin.

Nitoripe bi nwọn ba wipe ki o ma bọ nilu Japan, jamba ni lati sẹlẹ nitoripe a ti gbọ nipe awọn Japan pe nwọn ti fi ọkọ abẹ omi si ọna.

Rogbodiyan na tunbọ wa gbojikan silẹ Tokyo nigbati nwọn gbọ wipe ilẹ Japan ati awọn Yankees ti ba ara wọn dọrẹ. Gbogbo ilu bẹrẹ si rọ girigiri, awọn ọmọ University ati awọn omo ile ẹko giga tuto aoke nwon si fi ọju gba, nwon si ha! kilo ṣabu tẹ won yi.

Nigbati Ogbeni Nobusuke ti iṣe Prime Minister ilẹ Japan ri gbogbo nkan ti o nṣelẹ nwonyi ian rẹ bajẹ gidigidi, o ni sibẹsibẹ, awọn ara ilu on koiti mo iyi on, awon ko si ti mo iyi ohun ti on se fun wọn, bẹni o binu, o kọ iṣẹ iṣẹlu silẹ, o si yẹra kuro ni aria ilu. Iti digba ti agbari wọn ti o nghona nisisiyi ba tuta ki o to wa pe won ba sọro.

---


**Kere o!**

A ti ni oriṣiriṣi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdijẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, t'ọkunrin ati t'obinrin ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORE

7 Egerton Road, Lagos


## Ologbo Ko Nse Egbe Ekun

Lati ọwọ Eṣọ (Apa Kẹrin)

Aiya Ẹkun ja nigbati o gburo ayinike, o bẹrẹ si ṣe kayefi wipe kini ohun ti o nlẹ Ayinike Ayinipada Ẹkun tun ma ọkan le o wipe, o da mi loju wipe Ologbo ko le pa mi ṣa. Nwọn ni ki Ologbo jade, ki Ẹkun paapa jade, nwọn ni ki awọn lo ṣe ọdẹ kawo.

Ni awọn mejeji ba bẹrẹ ọdẹ ṣiṣe. Ki Ẹkun to pa ẹyọ kan, Ologbo ti pa bi iwọn mẹta tabi mẹrin. Ariwo sa gee e nigbogbo awọn ẹranko ba bẹrẹ si gbọwọ Loko Ologbo ti awọn si nwipe kai! ọkunrin ni ọ.

Inu bi Ẹkun tobẹ gẹ, ti o fi dide to Ologbo lọ, o wi fun pe, nsis yi iwọ lẹ fi ye mi pe irẹ ni agbara ju mi lọ, kini iwọ ni ti o si gbe oju le tobẹ ti iwọ kekere yi lati ma ba mi du oye? Ologbo dahun pe ṣe mo iṣe fun ọ, nigba kan wipe, Alaraku le mu eṣọ didakẹ ni Erin dakẹ.

Nitoto ni mo kere si ọ, ṣugbọn ni to akukan lu rẹ, kikere si abẹrẹ kere adie ko gbọdo gbemi, iyen ṣe emeṣẹ.

Ẹkun yọju si awọn ẹranko o ni fun wọn pe, ọla ti eyin lo mọ nti on bi bẹkọ, on yio ti sọ fun yin, on yio si ti faya pẹrẹpẹrẹ. Ologbo dahun wipe, iro! tapa lo fi eyini se. Ṣe ayinike ti emi mọ, ti iwọ na si mọ ti eyin o mọ mọ, iwọ ba mọ ayinipada rẹ bi?

Gbogbo ẹrọ akin ti Ologbo nse ide lẹnu si ma ki inu awọn ẹranko dun, tito nla si bo Ẹkun mọlẹ. Inu Ẹkun bajẹ wipe kini li a ti gbọ ewu pe on pelu Ologbo niyi papọ.

Bẹni Ẹkun ta bẹẹ sita, o si ki Ologbo mu bọ. Ologbo si afe to ọ lọ, awọn ẹranko ni ki Ologbo ma dahun, sibẹsibẹ o lọ, ni ija ba bẹrẹ.

Bi Ẹkun ba wipe ki on mu Ologbo yio ra si abẹ Ẹkun. Awọn mejeji ti nṣe bayi ọjọ pẹ, nigbati o ya di Ologbo sare siwaju, Ẹkun gba tele, o subu, o fi ẹhin lele.

Bi Ẹkun ti sare mọ lati fi ẹnu mu ni ẹrun ni Ologbo tito si Ẹkun lojo, oju Ẹkun si fọ.

(Koiti pari)

---

## IGBEYAWO OMOBA MARGARET NINU ILE ISIN NLA TILU LONDON



Awon ero ti o pọ ti a nwo ninu aworan yi ni awon ẹbi, ibatan, ojulumọ, ara ọrẹ, ti nwon wa sibi Igbeyawo Ọmoba Margaret ninu ile isin nla ti Westminster Abbey, ni igboro ilu London.

Ogbeni Antony Armstrong Jones ti o duro lowo osi ni oko Iyawo (Bridegroom,) Ọmoba Margaret ni Iyawo (Bride) ti o duro lowo otun pelu aṣọ kekere kan lori rẹ. Awon omo Iyawo (Brides maid) lo to ẹsẹ lẹhin toko-Iyawo. Ọkunrin ti o wa lẹhin won patapata ni ore oko Iyawo. (Bestman).

## Itan Bi Egbe Serafu Se Bere

(Apa Kẹrin)

Emi ti mo npa itan yi ti je okan ninu ọmọ egbe Serafu ri. Ni akoko ti mo fẹ wọ egbe na, Ijọ meta ni awọn pin si lakoko na, Ijọ ti Aladura ni Ita Balogun, Ijọ ti Mose Orimolade ti ise Baba Aladura ni Holloway Street tabi ni Doddy Alaja Street, ati ti Ijọ Captain Abiodun ni egbe ile Ogbeni Coker ni Balogun Street West.

Ki o to to ọdun 1931, awọn ariran ti pọ jaburata larin awọn Ijọ metẹta, Capt Abiodun ni Oluranlọwọ ni agbara emi iriran lati ta si ati gbogbo ẹmi, eni ti o si kọkọ ri iran na ni Oluwaji.

Lọdun ti a wi yi ni Abiodun (Majọr) so wipe, on ri iran wipe ki on kuro larin Ijọ Aladura ki on si lo da egbe ti on sile. Egbe ti o da sile na ni Agbo-Mimo Kristi ti o wa ni Okepopo.

Ni gbogbo ojo Alamisi ni awon omo egbe yi ma npe ipade lati gbo iran ti awon ri lojo aisun ọjọ (Saturday) Satide.

Ohun ti opo awon ariran ma nsaba ri ni akoko na ni wipe, egbe Serafu ni yio kari aiye.

Loju temi, o je ohun ti o yami lenu nigbati mo ba gbo ire oro ji pe bawo ni egbe ti yio kari aiye ye nigbati pin si ona meta. Oju ti yio bani kale ha le ti owuro se ipin bi?

Nisu Ijo ti Mose Orimolade, Baba Aladura ni Jesu Agege wa, Alagba Onamuga, Adeoye, Olugbemi, Seton, ati Amodu. Nisu Ijo ti Captain Abiodun, ni Iyafin Davies, Iya Isale-Eko, ati nisu Ijo Aladura ni Alagba Davis, J. A. Phillips, H. A. Phillips, Alagba Blaize, ati Okerowo wa.

---

## Ogagun Kan Jebi Esun Ese Nla Nile Amerika

—o—

A gbo irohin wipe Ogagun ile Amerika kan ni won te nibiti o gbe nta asiri ilu re fun awon ota, awon fi ojo sa ni kini awọn jagun-jagun, o si Jebi, awon ni ki awon lo yinbon pa.

Ko nse eyi nikan ni a gbo pe Ogagun na se o lo ko awon jandukn lo lati wa tako Ijoba, o fun won ni owo ati ota, awọn jandukn na je titara-titaru, tobẹ ge ti awon se Ijoba mo uti oke ti çelkan ko si le sekale.

Awon egbon Ogagun na ati awon aburo re ti o wa lowo nisu isa berudu yi ni awon fe yinbon pa Sugbon Ogagun na so wipe, awon jandukn ti on ko jo na, on se be lati fi gbeja Ijoba ni ko nse lati tako Ijoba.

On ko awon jandukn na jo lati wa ran Ijoba lowo si elatako won. Sugbon Ijoba ko gba oro re gbo.

---

## Adamodi Omo Alabojuto Bank W'ewon

— o —

Ọdọmokunrin ọdọran kan ti o fi jibiti gba Ponun mewa ni ile mewa lowo enikan lo so nigbati awon fe ra mo ewon wipe Alabojuto (Director) ti Central Bank ni baba on.

Ewon ti awon olopa ka mo lowo si wipe, o nfi ara re han kakiri wipe Aseju awon Onisowo ati ile Amerika kan ni on ise, o si tilo kakiri ibi lati lu won ni jibiti, o wipe awon egbe yi le ni oka won nile Nigeria.

Ọdaran yi bere jibiti re, nipa wipe enti o ba lati mu owo wa ti on yio gba gbogbo ni wa nigbati awon Oyinbo na ba de. A gbo wipe opo awon ti ko rikan sekan (Applicants) bere si mu oriṣiriṣi nkan wa bi adie, tolotolo, pepeiye, a ko tile siro iwonyi, owo ti o gba ni iru ona bayi je Ponun mewa. Adajo ni ki o lo si ewon osu mejidilogun. Tabi e ko ri aiye omo Manager bayi?

---

## Awon Omo Ile Eko Meji Mba Ara Won Soro

Awon omo ile eko meji mba ara won soro iṣhin ti awon jade kuro ni ilewe ti owuro, awon jijo nko ere ẹin lo sile. Eni kini bere lowo enikeji bayi pe :—

Ekini... Talo ni adie ti mo ri lowo re lana?

Ekeji... Emi ni mo ra lati kekere ti mo toju re dagba

1st... Hanin! ko si se amodi titi o fi di agbebo bayi?

2nd— Losan ojo kan, ti ojo nro, emi ko mo pe o ti je lo

1st... Se o sare pada wo ile nigbati o ri pe ojo mbo?

2nd...Kini! Hun, o bo si kete, ojo si pa o si bere si ku.

1st—Bawo lo tise yo o?

2nd...Baba yo fun mi lalfara pa. Nigba ti mo gbe e, gbigbon lo ngbon.

1st—He, o maṣe o, o fẹ ku niyen.

2nd...Kini nje bẹ! ko tan ku rara, Iya ni ki ndana fun u, mo dana fun, o si nyana

1st—Ha! o fe dana sun u ni, yio ku

2nd...Kini! nigbati mo da ina fun u o si nya ina, nigbati oju re wale o je agbado o tun bo soda o nlo tan ile.

1st...Se adie ti o nwi pa ni eyiti o ko awon omo re deni ti mo ri l'owo re ni ijeta.

2nd—Beni ni akoko yin re, o ye mewa o pa mẹsan e si fi okan de ile.

1st—Maṣe pa okan ninu awon omo re ki o fi se ase oje ibi re ninu Oṣu October.

(Wa yoo l'oju ewe keji)




## AWỌN ỌMỌ ILE ẸKỌ MBA ARA WỌN SỌRỌ

(o bere loju ewe kefa)

2nd – Ndao, iwo ko me pe nigbati Oluko agba fi dandan le wipe eni ti ko ba wo aṣọ ilewe wa ni akoko ti a ba wo ilewe nṣe ni nwọn o le jade, nigbana ni mo ko meji ninu awon ọmo re ta ti mo si da ewu.

## Darudapo Bere Nilu Japan

A ti ngbọ ninu awon iwe irohin kakiri wipe, Ọgbẹni Eisenhower ti iṣe Babanla ilẹ Amerika rangẹ si awon ara Japan pe, on mbọ wa be won wo irepọ.

Ori awon ọmọ Akẹkọ ilẹ Japan gbona si eyọ yi, nwon ni irepọ kan pelu awon Yankees (Amerika).

Ṣugbọn pẹlu gbogbo irọkẹkẹ yi Eisenhower sa mbọ ni ilẹ Japan ni. O ya nilẹ China, nitoripe ilẹ ni yio kọkọ kan ki o to de Japan.

Nigbati o kuro ni ilẹ China o rangẹ si Hirohito ti iṣe Ọba Japan, pe ki o pada on loju ọna. Ọba na si pari adehun irepọ pelu Eisenhower.

Bi Hirohito ti pada dele, ti awon eniyan si gbọ wipe Ọba ti ba awon Yankees ṣe adehun irepọ, werewere ni irohin ti tan kakiri, ilu ti daru.

Gbogbo awọn oṣiṣẹ Reluwe bẹrẹ da iṣẹ silẹ, P and T da iṣẹ silẹ, awọn Olopawo, Ulọgẹ Town Council gbogbo won ti bẹrẹ da iṣẹ sile gbogbo awon omo akeko ati awon ti o wa ni

(Wo yoku loju ewe Kejo)

## IPONRIKU PA ELENMỌ

(O bere loju ewe kefa)

yio fere je wipe gbogbo awon Dankare ilu Ibadan lo iṣẹ ichin, ti gbogbo won yio mu iṣan ati aṣẹ dani, ko si ṣaiti awon omo Ịṣhin egungun lo ei na.

Egungun miran tun mbọ ni Abeokuta ti nwon npe ni Ipọnriku. Ọgbọ ni Egba ati Ibadan nṣe odun egungun won

Ọkunrin ti a gbe Ipọnriku nṣe iṣẹ ni odun kan ti awon nṣe odun egungun ta iponriku ni Ibadan ni awon ọmọ ehin Elenmo lo ta Ipọnriku. Ẹsan yi ni Ipọnriku fẹ gba ti o fi lo gbe agi tire wa lati Abeokuta. Lojo ti Elenmo fe jade ni Iponriku lo ko awon obinrin

(Kosi pari)


## ARADAN NERVIGORA

Ogun ele pataki fun imarale agba ati aremọ pipe fun awọn aliya pupọ. O dara fun inu rirun, ele dodu, isokun oju, gbigbon owọ, ailesun, allokun ninu ati iruf̣e arun bawọnni, O je alldewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣe ku bi ọjo". 5/6 pere pẹlu owo ọkọ 1/6 e.g. 7/- Post Free.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

112, Denton St, 18, Denton Bridge Street,
P. O. BOX 2, Ebute-Metta.

Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.





## Okan Ninu Awon Olowo Arakuyamu Salaisi

Irohin kan wa wipe, okunrin kan Ọgbẹni John B. Kelly agba ti iṣe ọkan ninu awon olowo arakuyamu ilẹ Amẹrika salaisi ninu ile re ti o mbe ni ilu Philadelphia, nigbati o dagba di ẹni ọdun odun gere.

On ni baba to bi Ọmọba Grace Monaco. A gbọ wipe ki o to jaja wa ku yi o ti mbẹ larin amodi fun igba pipẹ ati pe aisan na yọ ọ lẹnu pupọ.

Nigba ewe Ọgbẹni Kelly ki o to wa di olowo arakuyamu yi, iṣẹ Birikila lo kọkọ ṣe. Lati ibe lo ti bere si di iji nitori iṣẹ re kọrọkẹrẹ titi ti o fi wa di Milonia (Millionaire).

A gbo wipe ọkunrin olowo na je arewa pidgidi, be na si ni Grace ọmọ re, ewa re pọ to te ge ti nwon fi fun ni oye ọmọba.

Awon omo mejeji ti olowo na fi sile ni ọmọba Rainier awon mejeji dabi ere, ewa won po gẹgẹbi ti ba won.

# Oloye Okotie-Ebo F'owo Siwe Egbeta Oke Ponun



Awọn meji ti a nwo ninu aworan yi, ti owo osi ni Reginald Maudling ti iṣe Baba egbe Igbimo owo siṣe (trade) nilu Oyinbo ati Oloye Festus Okotie Ebo, ti iṣe alabojuto gbogbo owo ti Ijoba apapọ nilẹ Nigeria.

Awọn mejeji gbowọ lowọ ara wọn nigbati nwọn pari adehun lori egbeta oke Ponun ti Ijọba ilu Oyinbo Gẹẹsi fẹ ya Ijoba Apapọ ti ilẹ Nigeria nigbati a ba gba ominira ni ọjọ kini oṣu October odun yi.


Always ask for
'DE FACTO'
the bread with the appetising flavour

## ALAKOSO ILẸ LIBERIA NILU IBADAN

(o bẹrẹ loju ewe kini)

ema ti awon lo p de Baba ẹgbẹ ti iṣe Alakoso ilu Liberia na nitosi Goverment College nilu Ibadan.



Ichin na ni awon kori si ile igi mo. Ibẹ ni Ọlọla Gomin Rank ee ti dide lọ ki alejo na, Ichin na lo lọ ṣe abẹwo awon emo egun ti o wa ṣe ẹsẹ f n u. Diẹ



nino awon eniyan pataki ti awon lọ ki ni ọdọ agba, Dr. R. Y. Hedges, Sir Adesoji Aderẹmi Ọba Ile Ifẹ, Ọmọba Adeleke Adedoyin. C. D. Akran. S. L Akintola. D. C. Osadebay ati ọpọ enia ti a ko le darukọ.

## AYIPADA BERE NWO LE ENIA DUDU

(O bere loju ewe kini)

Gbogbo agbara iṣẹlẹ ati lori iṣẹ Ichin ni o wa ni ikawọ rẹ gẹgẹbi ti Baba Ẹgbẹ ilẹ America.

Ẹyi wu wa o.

## Alhaji Rufus A. Adeshina Arrived From Mecca

Alhaji Rufus Adebayọ Adeshina, Z.Q., Managing Director of Messrs. Brewaco (Nigeria) Trading Company whose company is a copartner in the proposed £500,000 Tinned Tomato Factory and two other Industrial companies soon to establish in Nigeria, arrived in Nigeria, arrived back in Nigeria last Wednesday after completing a wide scale tour of Europe and the Continent on business trip.

Alhaji Adeshina who curtailed his tour to attend this year's Holy Pilgrimage for the first time arrived in the same plane with his wife, Alhaja Nimota Asabi Adesina, who also left for Mecca late in May for a Holy visit, and they also visited the Holy Land of Jerusalem and Jordan (Qudus).

Asked how successful was his business tour, the Alhaji said it was an "exalted success" and asserted that it was very curious to note from telegrams despatched to him in London by relatives that there had been a wide scale rumour that he and his wife died in the out-break of Missile in Mecca. He further added that he would wish themselves indentified to the public through this media that nothing of the sort befell them during their pilgrimage. Such remour, he claimed "was imaginary and false" adding that it must have sprung from wicked quarters.

When further asked when the Tomato Canning Industry will commence business, he replied that he had concluded final negotiations with the foreign partners to the deal and that the technical expert sponsored by the home office will arrive in Nigeria any time after Nigeria's Independence Celebrations in October.

The couple were met at the Ikeja airport by relatives and friends who had been too eager to see them arrived as a result of the unconfirmed rumour of their death ... ce.

## Oba Gesi Ndabira Lori Esin



Pẹlu ariya ati ẹrin muṣẹ ni Ọba Elizabeth Keji, fi ndabira lori ẹṣin ti a nwo aworan rẹ yi rekọja ni gbalasa ọdan ti ẹṣin asare ni Berkshire nilu Oyinbo. Awọn eni-ọla idile ọba pẹlu rẹ.

Alaiyelowa na jẹ ẹniti o fẹran ẹṣin gigun, nigbagbogbo ti nwọn ba ti fẹ sare ẹṣin ti Ascot ni ọba ma nṣe bẹ.

## DARUDAPỌ BẸRẸ NILẸ JAPAN

(O bere loju ewe keje)

Universities ilẹ Japan lo ko igi ati kumọ lọ di awọn igbimọ mọ inu ile igbimọ lati fihan wọn wipe ilẹ Japan ko wa irẹpọ kan pẹlu awọn Yankees.

**HINDU SANSARA'S**

**Religious Art Jewelleries**



HINDU SANSARA ... London ... England

**NI IRANTI**

**Iya Wa Owon**

Jane Loko

Ẹniti o dapọ mọ awọn Mimọ ni ọjọ keji oṣu July, 1955.

Sun're Mamma wa Sun're.

AWA ỌMỌ RẸ